E MA KA IROHIN IMOLE KI E SI MA POLOWO OJA YIN SINU RE

# IRỌHIN IMỌLẸ

MOTTO: IMỌLẸ DE, OKUNKUN PARADA.

READY FOR SALE
Iwe Arofo ti -:
ANỌYIN LOHUNBI-ỌMỌGE- IMARO
APA KETA
LATI ỌWỌ
G. A. SOWUNMI
Price 2/-
Modupe Press
16, Bamgbose Street,
Postag Extra

VOL. I No. 38, WEDNESDAY MARCH 19, — MARCH 25, 1958 KỌBỌ KAN

# Womi-womi Kan Woya Ija Pelu Eran Omi Ninu Odo

Eko

Agbọ irohin wipe wọmi-wọmi kan bere wipe, on fẹ ki ọga on ba on wa ọbẹ oloju-meji kan ki on mu dani nigbati on ba fẹ wẹ odo ni ọla, ọga rẹ bere pe, kilofa? odahun pe, yio ma rii nigbati nkan na ba se tan.

Lọjọ keji, nwọn fun ni ọbẹ oloju-meji o tẹ bọ apa rẹ, o si wọmi lọ, koju iwọn wakati kan lọ, ti wọmi-wọmi na gbiya ninu odo pẹlu eja nla kan ti nwọn npe ni Adede.

Gẹgẹbi irohin ti wọmi-wọni na muwa, o sọ wipe lojojumọ ti on ba ti nsisẹ lọwọ ni Ẹja Adede na yio wa bo on mọlẹ, yio si fẹ lati fi iru rẹ ta on, sugbọn asọ ti on ko wọ ko ni fun laye, on pinnu lati fi opin si ẹranmi na nitoripe nitosi ibiti on gbe nsisẹ ni awọn tio nwọ omi lọ wa yanrin gbe wa, ki o ma ba lọ se wọn lese.

Wọmi-wọmi na sọ pe, nigbati o tun de takọ ti abo ni, nse ni eyi abo bo on bo on mọlẹ sikan, on fa ọbẹ yọ, o ya gbogbo abẹnu rẹ ni ọbẹ, ako re si salo nigbati mo tawọ obe si.

Nigbati awon ti owa ni oke ṣakiyesi pe isoro wa fun womi-womi na, ni won ba faa gun oke.

## AWON IWE KOSEMANI

Iwe Adura Akanse 3/6d
Iwe Ilana Esin Ojisẹ nla Muhammad 3/6d
Kurani Esumẹta ti a tumọ si Yoruba 10/6d
Odu mẹrindinlogun 10/6d
Iwe Aniyan a ti Nofila Oru Oṣu Awẹ 5/6d
Iwe Egbogi Ajẹbidan 20/-
Itan Aladun 3/-
Gbedegbeyọ Hausa 3/-
Ajiran Ilu Oku 3/-
Itumọ ala kikun 5/6d
Iwe Owe Yoruba 3/6d
Psalmu Isẹgun Ajẹ ati aiye 17/6d pẹlu Turari lọfẹ
Iwe Itumọ Ala ati Ami Ara 3/6d
Afọṣẹ Iṣẹdalẹ Yoruba ati Psalm Ajẹbidan 2/6d

Akiyesi:- Ọpọlọpọ onibara wa ni ko mọ ile-iṣẹ wa n Mushin, a fi eyi si eti igbọ wọn pe ki wọn ma lọ ra POSTAL ORDER ni POST OFFICE pẹlu Stamp 1/- ki wọn fi ranṣẹ si wa, nwọn yio si ri ọja wọngba kia-kia.

Fi owo ati Stamp 1/- ranṣẹ fun gbigbe ọja rẹ pada
J.O. SHOYINKA c/o Post Office Ebute Mett
Tabi
8, Ojo Road (Oduabọrẹ) Mushin,

A le ri iwe yi ra ni ọdọ Olotu Irohin Imọlẹ 16, Bamgbose Street Lagos tabi ọdọ J. O. Shoyinka
, Ojo Road (Oduabọrẹ) Mushin

## EMMANUEL FOLARIN ALABI DI OBA ADJAME



ABIDJAN.

Irohin koto afojuba ni inawo ti awọn ọmọ Ejigbo ti o mbẹ ni adugbo Adjame ṣe ni ọjọ Ọjọbọ ti iṣe ọjọ kẹtala oṣu February 1958, ti a fi Alagba Emmanuel Fọlarin Alabi, jẹ Oye Ọba Yoruba si Adjame ninu ilu Abidjan (Cote d' Ivoire ) nilẹ Farase.

Ki o to to agogo mẹfa owurọ ni ẹsẹ tọmọde tagba ti pe ṣanṣan sinu ile Baba wa na. Nigbati ẹsẹ awọn ijọ Onigbagbọ ati ti Musulumi pe tan, Ọgbẹni Samuel Toki ti iṣe alakoso Ijọ Ọnigbagbọ, o dide, o fi adura kikun bẹrẹ ariya na. Lẹhin adura, Ọgbẹni John Gbenro dide o fi Alagba Emmanuel Fọlarin Alabi han gẹgẹ bi ẹniti gbogbo Yoruba ilu na yan ni Ọba fun Yoruba. Ninu ọrọ apọnle rẹ, Ọgbẹni Gbenro sọ ni asọyanju wipe, ọmọ bibi inu Ologbe Ọba Akinjọla Alabi ti ilu Ejigbo nilẹ Naijiria ni ẹniti a fi jẹ Ọba yi nṣe ati wipe ki a to yan ni Ọba yi ni ẹnikẹni ninu ilu Abidjan ati agbegbe rẹ ti mọ ọ ni Atọbatẹlẹ. Nihin ni Ọgbẹni Gbenro sọ ọrọ re de, ni gbogbo awọn to pejọ dide, nwọn si wolẹ fun ọba pẹlu gbolohun :- Kabiesi O ! Ọba Alaiyeluwa !!.

# IMỌLẸ

ESIN ỌRỌ WA:- IMỌLẸ DE OKUNKUN PARADA

*EDITORIAL WORKS & OFFICE*

**16, Bamgbose Street, Lagos**

**Telephone:- 21985**

*London Office:-*

*Sunday Ayorinde:- 5, Hemming Street London E. 1.*

UNITED KINGDOM REPRESENTATIVE

PUBLISHING DISTRIBUTING CO. LTD. MITRE HOUSE

177, Regent Street, London W. 1.

FUN OWO "IROHIN IMỌLẸ" ỌDUN KAN

EKO— Ṣile Mẹrin ati Kọbọ Mẹrin (4/4d)

Ilu miran ni Naijiria ati Oke-Okun, Ṣile Mẹfa ati Kọbọ Mẹfa (6/6d)


# ADETOKUNBO, O KU ORI 'RE O.

Ọrọ Bibeli ki yio ṣai ṣẹ, bi o ti wu ki ọjọ pẹ to. Bibeli sọ bayi pe, Iwọ Esaw maṣe binu lati ma sin arakunrin rẹ Jakobu, nigba o ba ya, iwọ yio bọ ajaga kuro li ọrun, iwọ yio si di Ominira. Njẹ ohun ti Bibeli wi ko ha ṣe le wa lori bi? Ọṣẹ.

A ko gbọ ni itan lati ẹnu awọn Baba wa pe, Iran Enia dudu kan di Adajọ agba fun ilẹ Naijiria ri. Ṣugbọn lẹnu lọlọ yi, nigbati Sir Foster Sutton Adajọ agba atijọ lọ fun isinmi ni Gomina Agba ba fi ipa yi da Sir Adetokunbọ Ademọla lọla.

Ṣaṣa enia ni igboro Eko, Ebute-Mẹtta, Abeokuta ati awọn ilu miran ni ko mọ Adajọ agba titun yi nigbati o nṣe adajọ kekere ni Eko. A. B. 1. ni adape orukọ rẹ, nitoripe A. B. 1. ni mọto ti o nlo ni igbana atipe ọmọ bibi inu Baba Kabiyesi Alayeluwa Ademọla Keji ni iṣe, eyi papa tun jẹki Adajọ tirẹ'gba iyi pupọ nigbana. A bi ọlọla yi ni Oṣu Feb. 1906, o bẹrẹ ẹkọ rẹ ni ile Iwe Aguda, lẹhinna o tun fun Ẹkọ giga ni St. Gregory's College ati Kings College ni Eko. Gbara ti o jade ni Ile Ẹkọ giga yi, o tẹ ọkọ Ilu Oyinbo leti lati tun lọ kọ Ẹkọ giga julọ ni Ilu Oyinbo ni ọdun 1927, eyiyi ni iṣẹ Amofin, o si gba oye kikun ni ọdun 1932.

Ni ọdun 1957, ni ọba Ilu Oyinbo fi oye Sir da lọla on ati Baba rẹ Alayeluwa Ademọla keji wa di ọgbọgba ninu oye.

Ni ọdun 1939 ni Sir Adetokunbọ Ademọla gbe omidan Kolọworọla Moore ni iyawo.

A ko tun le ṣai fẹnu kan Oniṣegun agba wa Dr. Manuwa bakanna, Oyinbo ni o ti nwa ni iru ipo bayi ri, ṣugbọn nisisiyi on li a fi da lọla, nitotọ a wa gba daju pe Ominira otitọ de. Gbogbo ẹyin ọmọ Liṣabi jakejado agbaye, e ku ori re fun ti omo yin ti di Adajo Agba Najiria. Baba Kabiyesi, e ku ori re fun omo re ti odi Adajo Agba, awọn yoruba a ma pa lowe bayi pe :—

"Ki iya akoko to ku, enu ọmọ re a to igi so".

Ọmọ-oba Tokunbo, oye a mori o, a ki ridi okun, a ki ridi osa, omọ onigedegede ki jeki a rid'on, ko s'eda to mo ibiti oyin fi nse afara. Kabiyesi o! Adetokunbo Ademola, omo araiye ko ni ri e gbese lagbara Odua


DIRECT YOUR PRINTING JOBS TO:-

MODUPE PRINTING PRESS

16, Bamgbose Street, Phone 21985

LAGOS.


# Iwe Si Olotu

## Ilu Ikotun Nfe Idagbasoke

Inu mi yio dun bi e ba le gba mi laye lati sọ ẹdun oka wa fun Ijọba Iwo Orun Naijiria, a nfẹ Ile-Iwosan, Post Office, a si tun nfẹ ki wọn da oda si titi wa.

Awọn nka mẹtẹta yi lo nje wa ni iya, Inu wa yio si dun ti awọn Ijọba ba ba wa mojuto ọrọ yi, ki wọn si fun wa ni ohun ti a nfẹ.

Emi ni
K. A. Ayinde.
Ọmọ Oke Imọle.

## Abule Igbusi nfe Iranlowo Ijoba

Abule yi je ilu kan ni gbogbo agberiko ti obẹrẹ lati Songo titi de Ifọ wọn ko si fi owo ori wọn falẹ rara. Gbogbo wọn fẹrẹ le jẹ ọpẹ (Action Group) tan. Ninu ibo ti wọn di ni eṣi ẹgbẹ ọlọpẹ lo leke nibe, wọn si nmura si ẹgbẹ na gan. Abule Igbusi nfẹ ki ẹ la titi de abule yi, atipe wọn fẹ ki Ijọba ba wa mojuto awọn ole ti o wa ni agbegbe Abule yi.

Ẹjọwọ ẹgba wa o, emase ta ọrọ wa nu o.

Inu wa yiO dun bi ẹba lese ohun ti o bere lọwọ yin yi. Olotu modupẹ aipe yio yẹ gbogbo wa.

Emi ni
Thomas O. Soyinka.
Ebute-Mẹtta Lagos.

## Mo kin Otelemuye lehin

OLOTU,

Jọwọ gba mi laye ninu iwe rẹ oloyin mọmọ lati ki Otẹlẹmuyẹn lẹhin nipa ọrọ iyawo fifẹ ni iwọ orun o nira pupọ ju tobẹ ti o fi jẹpe inira ati ipọnju ni o njẹ fun ọkọ ati iyawo ti iyawo ba delẹ tan, ipọnju na ki tan nilẹ ki wọn to bi ọmọ, ọmọ na a si tun ji si nu inira, bẹbẹ lọ iṣẹ ati osi na, afẹ wa di iran.

Gbogbo wa ti mọ pe ti ara ba dẹ ọkọ, iyawo nilati gbadun, nitorina a bẹ ijọba ipinlẹ iwọ orun lati tete ba wa mojuto iru iwa alebu bayi.

Olotu mo dupẹ aye ti o gba mi lati tun fi eyi se isileti fun awọn ijọba ipinlẹ iwọ orun, ọkọ ọba koni sayin lẹsẹ o.

E. O. Akinọla
4, Alase Lane
Mushin.

## Akiyesi pataki fun awon Ilu Ijomu

Ota si eti igbo emi pe ati gbogbo awọn Oro Ijomu a si tun ri ka ninu iwe irohin yi (irohin imọle) Wednesday ti 5th Feb. 1958 oju ewe keji ni pa ọrọ ti ọgbẹni ti o pe ara rẹ ni ọkunrinmẹta ti Ijomu-otun Oro sọ nipa awọn ara oro Ijomu. Emi gẹgẹ bi ọmọ ti abi ti a si tọ ni Ijomu oro, ti mo ṣi ge asoju ati asiwaju awọn Oro-Ijomu lodi si gbogbo ọrọ ti ọkunrin mẹta yi sọ, mo si tun fẹ ki gbogbo enia aiye yi mọ daju daju pe ko si ẹnikan ni gbogbo ọrọ ijomu ni ile ati oko ti orukọ rẹ amajẹ ọkunrin-mẹta lati Ijomu-ọtun-Oro. Ti ọkunrin bẹ ba si wa njẹ mo fẹ ko yọ si gbangba pẹlu gbogbo ohun to mọ nipa ọrọ ati Iselu Oro-Ijomu.

Emi ni
IREDE.
46, Docemo St., Lagos.

## Idahun si oro Ogbeni eniti o ni ife gigidi

Inu mi yio dun bi Olotu bale gba mi laye lati dahun si ọrọ ti Ọgbẹni ti orukọ rẹ njẹ Ẹniti-o-nifẹ ilu rẹ gidigidi, ọmọ bibi Okeya ti o jade ninu iwe ti 12/3/58.

O yami lẹnu lati gbọ pe ọrọ ti Mọkadamu sọ nipa ilu Okeya pe ko yẹ ki alejo mọ sọsi ọrọ ilu onilu. Kodẹ mọ dajudaju pe, ajoji kan kole mọ nipa ilu Okeya bi kiṣe arawa. Ọrọ ti iwọ ọgbẹ-ni wa sọ ti oruko re nje Ẹniti-o-nife ilu re. Iwo gan ni kofe ki ote Okeya pari rara. Pelu ogo Ọlorun yio pari nisoju re pato. Ni okunrin, lobirin, lomode, lagba ni otun ati ni osi mo be yin loruko Ọlorun ati Ojisenla Moamodu ẹyin omo Okeya e pe ara yin jo ki e pari ote ilu Okeya. Ti e ba gbo oro awon ti ko fe ko pari, e ko ni le pari re. Nitorina ki e pe ara yin jo, ke pari rẹ.

Emi ni,
N. A. ỌLAREWAJU
28a, Victoria St., Lagos

